# Kii Se Esin Lasan

Revd. Edward Omojevbe Eruteya

Ever-Flowing Grace Assembly

dupe lowo Re fun ise iranse inu iwe pelebe yii. O ti mu mi lati se agbeyewo ohun ti mo gbagbo. Mo ti rii ohun ti mo gba gbo kii se ona naa, ona kan lasan ni. Mo pinnu lati yipada si Jesu tii se Ona naa bayii. Mo gba o gbo gege bi Oluwa ati Olugbala mi; dari ese mi jin mi, we mi nu kuro ninu aisododo gbogbo ki o si gba mi sinu Ijoba re. Mo dupe nitori pe o gba mi la. Amin.

IMORAN MI: Lati akoko yii lo, rii pe o ni Bibeli kan ti o ko ba ni tele. Gbiyanju lati maa se asaro ninu re bi o se n gbadura pe ki Olorun la o loju lati ri ohun iyanu ti o wa ninu Bibeli (Orin Dafidi 119:18). Darapo mo apejopo awon omo Olorun ni adugbo re lati maa josin pelu won ni gbogbo igba (Heberu 10:24-25). Je ki oluso agutan ipejopo naa da o mo ki o ba lee se iribomi ti omi ati ti Emi Mimo fun o (Marku 16:15-16, Ise Aposteli 10:44-48). E di alabu-kunfun.

Lati kan si ile-ise iranse ti Olorun yan yii: Pe si: 0818-1304235, 0803-3952947, 0803-2460619.

Josin pelu wa ni: Eeer-Flowing Grace Assembly (Inc), Plot 12 Block 46, Ayetoro Housing Scheme, Oju opopona Oyo si Ogbo-moso, Agbegbe Oroki, Oyo. Inu re yoo dun pe O se bee. A npade ni: Sonde Agogo Mesan Owuro. Ojoru: Agogo Marun-abo irole. Satide Akoko ninu osu Agogo Marun-un irole ni Adura fun gbogbo Orile-ede, Satide to gbeyin osu Agogo mejila osan ni akoko Ironila-gbara/Wakati Igbagbo.

KII SE ESIN LASAN Lati Owo Edward O. Eruteya

Owe 14:12 Ona kan dabi eni pe o dara loju eniyan, sugbon opin re ni ona iku.

E

yi tumo si pe gbogbo eniyan ni o gba nnkan gbo. Iwo ti o n ka iwe pelebe yii naa ni igbagbo ninu ohun kan tabi omiran. Opolopo esin lo wa laye ti awon eni-yan ni igbagbo ninu re loni, ewo ni tire nibe?

Jije elesin kan ko ni o se pataki, sugbon ohun ti o se pataki ni pe nibo ni esin ti o gba n mu o lo? Se inu iku ni tabi inu iye? Eyi mu ki okan ninu owe Oba Solomoni ba oro ti o n so yii mu. Oba Solomoni so pe, Ona kan dabi eni pe o dara loju eniyan, sugbon opin re ni ona iku. (Owe 14:12). Ohun ti o gbagbo je ona kan ti o n to. Mo fe ki o mo pe iyato wa ninu ona kan ati ona naa bi o tile je pe o dabi eni pe o dara ni oju re. Sugbon ronu die lati mo ibi ti ona yii yoo gbe o de. Se inu iye ni tabi inu iku? Bi o fe bi o ko ohun yoowu ti o dabi eni pe o dara kii se pe o dara. O kan dabi ni kii se ohun gangan. Boya ni, eyi ko da ni loju. Ohun yoowu ti ko ba da o loju mase tesiwaju pelu re. Eyi wa fun o ni ise se lati ye ohun ti o gbagbo wo daradara. Kii se oro pe awon eniyan pupo lo wa loju ona yii, nitori naa mo gbodo tesiwaju ninu re, rara. Se ayewo daradara, nibo ni ohun ti o gbagbo yii n mu o lo. Bere si ni beere ibeere, ki o si mo pe isoro ti eda eniyan ni naa ni ese. Ese je egan fun eniyan (Owe 14:34b). Ibeere Kinni: Tani

oludasile ohun ti o gbagbo? Daruko re (ako tabi abo). Ibeere Keji: Se oludasile naa je elese bi emi ati iwo tabi ko lese rara? Se awari eyi. Ibeere Keta: Kin ni oludasile naa ti se lati gba iran eniyan la kuro ninu ese? Se awari eyi. Ibeere Kerin: Kin ni ete ti oludasile ni fun iran eniyan fun ayeraye? Se awari eyi. Ibeere Karun: Nje oludasile naa ni agbara lori eru, aisan, iku, emi esu ati Satani? Se awari eyi pelu. Ibeere Kefa: Se oludasile yii si wa laaye ti awon eniyan lee so pe awon ni iriri re? Se awari eyi. Ibeere Keje: Nje oludasile ni Ijoba kan fun awon olusin re? Se awari eyi. Ibeere Kejo: Kin ni awon eto tabi agbara ti oludasile ni lori Ona naa , kii se lori ona kan ? Se awari eyi. Ninu gbogbo awon ibeere yii, oludasile kan pere ni o yege. Jesu tii se ti igbagbo awon kristiani ni o yege ninu gbogbo ibeere wonyi. Oun ni Olugbala ti a ran wa saye lati Orun (Johannu 3:10-15). O ti se gbogbo ohun ti o to ti o si ye lati gba iran eniyan la kuro ninu ese. O fi emi Re lele fun iran eniyan (agutan naa) Johannu 10:11. O ku lori agbelebu; o ta eje Re sile lati we iran eniyan mo kuro ninu ese ki ese ma baa nipa lori wa (Romu 6:14). Kin ni o ti se pelu Olugbala ti a ran si o? O ku si owo re. O ti gbo gbogbo otito ti o ye ki o gbo.

Mo tun n tun wi pe: Jesu ko lese (Heberu 4:14-15, Johannu 8:45-46, 1 Peteru 2:2). Jesu ni Olugbala (Luku 2:10-11, Johannu 4:41-42). Jesu ni Ona naa (Johannu 14:6). Jesu wa laaye titi lai, O ni kokoro iku ati ipo oku lowo (Johannu 20; Ise Aposteli 1:1-3; Ifihani 1:18). Jesu ni Ijoba kan (Johannu 18:36, Luku 23:39-43). Jesu ni eni-isaaju ati eni-ikehin (Ifihan 1:17). Jesu wa laaye lati gba eniyan la titi de opin (Heberu 7:25). Jesu n dari ese jin (Luku 5:17-26; 7:47-49). Jesu ni asegun iku (Romu 6:9; Heberu 2:9-18). Jesu ni Oluwa ati Onidajo alaaye ati oku (Romu 14:7-9, Ise Aposteli 10:34-42). Jesu ni ajinde ati iye (Johannu 11:25). Jesu n wosan o si n ji oku dide (Matiu 4:23-25, Luku 7:11-17; Johannu 11). Jesu ni oluso agutan rere fun awon agutan (Johannu 10). O mo gbogbo eniyan o si mo ohun ti eniyan je (Johannu 2:23-25). Jesu n pada bo (Johannu 14:1-4, Ise Aposteli 1:9-11). Mase je ki a da o lagara nipa awomoni. Jesu nitori ri pe ko lonka. A gba o niyanju lati farabale yipada; yi esin re pada kuro ninu ona kan si Ona naa:.Yipada si Jesu lonii.

O ko lee maa tesiwaju ninu ese pelu Jesu ninu aye re (Romu 6:1). Nigba ti o fi igbagbo gba Jesu sinu aye re ni o gbodo bere si gbe igbe aye ti a kan mo agbelebu (Romu 6:6, Galatia 2:20). O je igbe aye ti ko gbodo teriba fun ese mo niwon igba ti a ti so eniyan di aaye ninu Jesu (Efesu 2:1-10). Beeni, bi o ti mura tan lati gba Jesu bayii, mo gbodo so eyi fun o. Mase je ki okan re daru nigba ti a ba ri awon ti won n pe ara won ni onigbagbo ninu Jesu, sugbon ti won ko gbe igbe aye won bii Kristiani. Opolopo won lo wa ninu ile ijosin, won n si awon eniyan lona nipa Ona naa. Bi o ti wu ki o ri oro tire gbodo yato si ti won iwo gbodo gbe igbe aye kristiani tooto, gba Emi Olorun ati oro Olorun laaye lati maa tun aye re se lojoojumo. Ni iseju die, gba adura yii pelu okan re. So pe, Baba Orun, mo